# IWOSAN ẸLẸMI ÈṢÙ ARA GÁDÁRÀ

## Marku 5:1-20

### ẸKỌ 79 – FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Enia li eyi ṣoro fun; ṣugbọn fun Ọlọrun ohun gbogbo ni ṣiṣe" (Matteu 19:26).**

**Òdi Keji Òkun**

Jesu ti n kọ́ ni lati inu ọkọ̀ lori Okun Galili. Ọpọ eniyan ni wọ́n wà leti okun naa ti wọn n gbọ́ awọn owe Rẹ̀, ṣugbọn O wi pe, "Ẹ jẹ ki a rekọja lọ si apá keji."

Ilẹ̀ awọn ara Gadara wa ni iha ila-oorun òkun, nibi ti ọkunrin kan ti o n fẹ iranlọwọ lati ọdọ Oluwa n gbé. Jesu mọ̀ nipa ọkunrin yii, gẹgẹ bi O ti mọ̀ nipa obinrin ara Samaria ẹni ti Oun yoo bá pade nibi kanga Jakọbu, nitori a kà pe, "On kò si le ṣaima kọja larin Samaria" (Johannu 4:4). Obinrin yii ti ó n gbé ni Samaria kò mọ̀ bi a ti n sin Ọlọrun. Alafẹnu-jẹ ẹlẹsin ni, ṣugbọn bi Jesu ti n ba a sọrọ o mọ pe ẹmi isin tootọ maa n ti inu ọkàn wá. A da a lẹbi ẹ̀ṣẹ rẹ̀, o si beere fun omi iye ti o n tẹle igbala. Nigba ti Jesu fi ara Rẹ̀ hàn án, oun kò gba A gbọ́ nikan, ṣugbọn o jẹri to bẹẹ ti a mú ọpọlọpọ awọn miiran wá sọdọ Rẹ̀. Bẹẹ ni o ri lọjọ oni pe Oluwa mọ awọn ti wọ́n n fẹ Ihinrere ti wọn si n fẹ iranlọwọ Rẹ̀. Oluwa ati awọn eniyan Rẹ̀ yoo sa gbogbo ipá wọn ki a ba le gba ọkàn kan là. Ni igba kan, angẹli Oluwa sọ fun Filippi, Ajihinrere, lati lọ si Gasa. O lọ sibẹ, o si ri ọkunrin ara Etiopia kan, ọkunrin alawọ-dudu ti o fẹ kọ́ nipa Oluwa. O n ka Ọrọ Ọlọrun, ṣugbọn kò mọ itumọ rẹ̀. Bi Filippi ti "wasu Jesu fun u," ọkunrin naa gbagbọ́, a si gba a là.

Bi Jesu ati awọn ti o wà pẹlu Rẹ̀ ti n rekọja òkun, igbi nla dide. Ẹru ba awọn eniyan naa pe awọn yoo rì, ṣugbọn O bá afẹfẹ wí pẹlu awọn ọrọ wọnyii; "Dakẹ jẹ," iparọrọ nla si dé. Jesu ni agbara lori gbogbo ẹda. Lai pẹ titi awọn ọmọ-ẹyin yoo ṣe ẹlẹri iyipada nla bi Oun ba ti paṣẹ idakẹ jẹẹ kan naa si ọkàn ati igbesi-ayé ọkunrin kan, igbi ẹ̀ṣẹ yoo si duro jẹẹ. Bi o ti maa n ri gan an nigba ti eniyan kan ba gbadura agbayọri si igbala ni gẹgẹ bi Jesu ti dá igbi duro ni Okun Galili.

**Ẹni ti o ní Ẹmi Aimọ́**

Ọkunrin kan ti o ní ẹmi aimọ́ pade wọn leti òkun. Ẹṣẹ ti ba igbesi-aye rẹ̀ jẹ́, titi de inu òye rẹ̀ paapaa – eyi ni pe, oun kò le ronu bi ẹni ti ori rẹ̀ pe. Kò si ẹni ti yoo fẹ maa gbé laaarin iboji, ṣugbọn ibẹ ni oun n gbé; kò si ẹni ti yoo fẹ maa fi okuta ya ara rẹ̀, ṣugbọn oun n ṣe bẹẹ. Ẹṣẹ maa n mu awọn eniyan ṣe bakan naa lọjọ oni: ẹlẹṣẹ n gbé laaarin awujọ awọn oku nipa ti ẹmi; ni igba pupọ ni o maa n ṣe awọn nnkan ti o ma pa ara rẹ̀ lara -- gẹgẹ bi mimu taba ati ọtí. Ẹṣẹ a maa mú ibanujẹ ati ijiya wá nipa ti ara ati nipa ti ẹmi pẹlu.

**Iranlọwọ fun Alaini Iranwọ**

Awọn ọrẹ ọkunrin yii ti gbiyanju lati ran an lọwọ, nitori wọn ti fi ṣẹkẹṣẹkẹ ati ẹ̀wọ̀n de e nigba pupọ. Boya wọn gbiyanju lati fi i pamọ sinu ile, ki wọn si dá a lẹkun lati pa ara rẹ̀ lara. Ẹmi eṣu ti o wà ninu rẹ̀ fun un lagbara lati dá ṣẹkẹṣẹkẹ ati ẹ̀wọ̀n naa. Dajudaju igbe rẹ̀ lọsan ati loru, mu ẹ̀rù wọ inu ọkàn wọn, ṣugbọn Jesu ni Ẹni kan ṣoṣo naa ti O le ṣe e ni ire, ti o si le dá a silẹ. A mọ̀ pe ko si ohun ti o ṣoro fun Jesu paapaa nigba ti awọn eniyan ko le ran ara wọn lọwọ tabi ki ẹlomiran ràn wọ́n lọwọ. "Enia li eyi ṣoro fun; ṣugbọn fun Ọlọrun ohun gbogbo ni ṣiṣe" (Matteu 19:26).

Awọn ọrẹ le gbiyanju lati ràn wá lọwọ. Wọn le waasu Ihinrere ati ohun ti agbara Ọlọrun le ṣe fun wa. Wọn tilẹ le ba wa gbadura, ṣugbọn Jesu nikan ni O le gbà wá kuro ninu ẹ̀ṣẹ wa, ti O si le wo àgọ́ ara wa sàn. Awọn ẹmi eṣu ti o wà ninu ọkunrin yii ni lati tẹriba fun agbara Oluwa. O sọ awọn ọrọ wọnyii: "Jade kuro lara ọkunrin na, iwọ ẹmi aimọ́," wọ́n si jade kuro lara ọkunrin naa. Nitori wọ́n pọ̀ pupọ o wi pe Legioni ni orukọ wọn (ẹgbẹ ọmọ-ogun ti o fẹrẹ to ẹgbaata – 6,000). Wọn bẹbẹ lati wọ inu agbo ẹlẹdẹ. Awọn ẹmi eṣu ni agbara, ṣugbọn nibi ti Jesu bá wà, ohun ti O ba wi nikan ni wọn yoo ṣe. Nitori Jesu gbà fun wọn, wọn wọ inu agbo ẹlẹdẹ, agbo ẹlẹdẹ naa tú puu, wọn si sare wọ inu òkun. Bakan naa ni i ba ti ri fun ọkunrin yii nigbẹyin, ṣugbọn Jesu ko jẹ ki eyi ri bẹẹ nitori Oun mọ̀ bi ẹmi kan ti ṣe iyebiye to.

Njẹ o le fi oju inu wo ọkunrin yii? O ti dẹruba awọn eniyan. Wọn le maa gbọ́ igbe ọkunrin yii lati inu iboji wá loru, wọn si mọ̀ pe o ni lati wà ninu irora nla nitori ọgbẹ́ ti o wà lara rẹ̀. Wọn kò le ran an lọwọ; ṣugbọn nigba ti Jesu sọrọ òye rẹ̀ pada bọ̀ sipo, o si dabi eniyan. A ti wo o sàn! Ro bi inu rẹ̀ yoo ti dun tó, ati bi yoo ti dupẹ lọwọ Oluwa to fun ohun ti O ṣe fun un!

Agbara eṣu pọ̀ pupọ, ṣugbọn agbara Jesu pọ ju ti rẹ̀ lọ. Ibi ti Jesu ba fun eṣu laye mọ lati dé ni o le de, ko le kọja ibẹ. "Nitori eyi ti Ọmọ Ọlọrun ṣe farahàn, ki o le pa iṣẹ Èṣu run" (1 Johannu 3:8). Wo Jobu. Nigba ti Satani pa ohun gbogbo ti o ni run, ati awọn ọmọ rẹ̀ pẹlu, Jobu kò bú Ọlọrun gẹgẹ bi Satani ti wi pe yoo ṣe. Lẹyin naa ni oowo sọ Jobu kikan kikan ṣugbọn o di igbagbọ́ rẹ̀ mú ṣinṣin, kò si kùn si Ọlọrun. Ohun ti Ọlọrun fun Satani laye lati fi ọwọ́ kàn ni igbesi-ayé Jobu nikan ni o le fi ọwọ́ kàn -- kò le ṣe ju bẹẹ lọ. Pẹlupẹlu, Ọlọrun fun Jobu ni ilọpo meji ohun ti o ni tẹlẹ ri (Jobu 42:10).

**Wọ́n Bẹbẹ pe ki O jade**

Nigba ti awọn eniyan ilu yii gbọ́ ohun ti o ṣẹlẹ wọ́n wá sọdọ Jesu. A le ro pe inu awọn ara Gadara yii yoo dùn pupọ lati ri i pe ọkunrin ẹlẹmi eṣu yii ti sàn, o ti wọ aṣọ, iye rẹ̀ si ti pada bọ̀ sipo. Dipo eyi, wọn ronu nipa ohun ini wọn ti o ti ṣofo – agbo ẹlẹdẹ -- wọn kò si naani iwosan ọkunrin naa. Awọn miiran maa n lọra lati yin Ọlọrun logo

fun iṣẹ ami ti O n ṣe fun wọn ati fun awọn ẹlomiran. A kò gbọdọ jẹ ki ọkàn wa kún fún aniyan awọn nnkan ayé yii. Bibeli wi pe, "Ẹ máṣe tò iṣura jọ fun ara nyin li aiye, nibiti kòkoro ati ipara ibà a jẹ, ati nibiti awọn olè irunlẹ ti nwọn si ijale: ṣugbọn ẹ tò iṣura jọ fun ara nyin li ọrun, nibiti kòkoro ati ipara kò le bà a jẹ, ati nibiti awọn olè kò le runlẹ ki nwọn si jale. Nitori nibiti iṣura nyin bá gbé wà, nibẹ̀ li ọkàn nyin yio gbé wà pẹlu (Matteu 6:19-21).

Bawo ni o ti ba ni ninu jẹ to lati kà pe wọn bẹ Ẹ ki O fi agbegbe wọn silẹ ! Jesu ki i duro nibi ti wọn ko ba fẹ Ẹ. Bi Jesu ti n fi ibẹ silẹ, ọkunrin ti a wosan yii fẹ ba A lọ. Ni aṣẹ Jesu, o duro lati sọ fun awọn ọrẹ rẹ̀ ohun nla ti Oluwa ti ṣe fun un. Dajudaju, bi o ti n jẹri, o rán wọn leti iru igbesi-aye ti oun ti n gbé ri: bi awọn ẹmi eṣu ti lagbara lori oun to bẹẹ ti ẹru ba awọn eniyan, ti wọn si n dá oun lóró. Ko si ẹni ti o le ran an lọwọ. Ni ọjọ kan o ba Olugbala pade, gbogbo nnkan si yí pada. Lai si aniani, ẹnu ya awọn eniyan! Wọn ko le ṣe alai gba a gbọ́ nitori kò si ẹni ti o le mu ẹ̀ṣẹ ati ibanujẹ kuro ninu igbesi-aye rẹ̀ afi Jesu.

Awa pẹlu gbọdọ jẹri, ki a si sọ fun awọn ẹlomiran pe Ọlọrun ti gba wa là, O si ti wò wá sàn, ki Oun ba le gba ọla ati ogo. Ẹni kan ni o sọ nipa Jesu fun ọ. Njẹ o ti sọ fun ẹlomiran bi?

Bawo ni inu ọkunrin yii iba ti dun to lati wà pẹlu Jesu! Ṣugbọn o mọ̀ pe nipasẹ igbọran ni ayọ̀ tootọ ti n wá.

**AWỌN IBEERE**

1. Sọ ni ede ti rẹ itumọ "ọkunrin ti o ni ẹmi aimọ"
2. Ki ni ṣe ti o n gbé laaarin iboji?
3. Ki ni ṣe ti a pe awọn ẹmi eṣu naa ni Legioni?"
4. Bawo ni a ṣe wo ọkunrin naa san?
5. Ki ni ṣẹlẹ si agbo ẹlẹdẹ naa?
6. Ki ni ṣe ti Jesu fi ibẹ̀ silẹ?
7. Ki ni ṣe ti ọkunrin yii duro dipo ki o tẹle Jesu?